Mo fi Ọlọhun bura, ki Ọlọhun fi arákùnrin kan ṣoṣo mọna latara rẹ, o loore fun ẹ ju ki o ni ràkúnmí pupa lọ

Lati ọdọ Sahl ọmọ Sa'd- ki Ọlọhun yọnu si i- dajudaju ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ ni ọjọ́ Khaibar pé: Dajudaju maa fun arakunrin kan ni asia yii ni ọla ti Ọlọhun maa ti ipasẹ rẹ fun wa ni iṣẹgun, o nífẹ́ẹ́ Ọlọhun ati ojiṣẹ Rẹ, Ọlọhun ati ojiṣẹ Rẹ naa nífẹ́ẹ́ rẹ", o sọ pe: Àwọn ènìyàn sùn ní alẹ́ náà tí wọ́n ń jiroro laarin ara wọn tani wọn yoo fun." Nígbà ti ilẹ mọ́, àwọn èèyàn lọ ba ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ti ọkọọkan ninu wọn si n fẹ ki wọn fun oun, o sọ pe: "Ibo ni 'Ali ọmọ Abu Talib wà"? Wọn sọ pé: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, ojú n dùn ún. O sọ pe: "Ẹ ranṣẹ si i", wọn si mu u wa ni ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- wa tutọ́ si oju rẹ mejeeji, o si ṣe adura fun un, o si gbadun gẹgẹ bii pe inira kan kan ko mu u, o wa fun un ni asia náà. Ali wa sọ pe: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, ki n maa ba wọn ja titi wọn fi maa da bii wa? O sọ pe: "Maa lọ ni pẹlẹpẹlẹ titi waa fi dé agbegbe wọn, lẹyin naa pe wọn sinu Isilaamu, sọ nnkan ti o jẹ dandan le wọn lori ninu ẹtọ Ọlọhun fun wọn nibẹ. Mo fi Ọlọhun bura, ki Ọlọhun fi arákùnrin kan ṣoṣo mọna latara rẹ, o loore fun ẹ ju ki o ni ràkúnmí pupa lọ".

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ fun awọn saabe nípa ìṣẹ́gun awọn mùsùlùmí lori awọn Juu Khaibar ni ọjọ keji, ìyẹn maa waye lati ọwọ arakunrin kan ti oun maa fun un ni asia, oun naa ni àsíá tí àwọn ọmọ ogun maa n fi ṣe àmì wọn, Ati pe arakunrin yii ninu awọn iroyin rẹ ni pe o nífẹ́ẹ́ Ọlọhun ati ojiṣẹ Rẹ, ti Ọlọhun ati ojiṣẹ Rẹ naa si nífẹ́ẹ́ rẹ, Àwọn saabe si sùn ni alẹ ti wọn n jíròrò ti wọn si n sọ̀rọ̀ nipa pe tani wọn maa fun ni asia naa? Ni ti ìfẹ́ si iyì ńlá yii, Nigba ti o di àárọ̀ wọn lọ sọ́dọ̀ Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a-, gbogbo wọn ni wọ́n n nírètí pé àwọn á gba iyì yìí, Ni Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- wa beere nipa 'Ali ọmọ Abu Talib- ki Ọlọhun yọnu si i-? Wọn sọ pé: O rẹ ẹ, ojú rẹ mejeeji n dun un. Ni Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ba ranṣẹ si i, wọn si de pẹlu rẹ, o wa tu itọ si oju 'Ali mejeeji ninu itọ rẹ abiyi, o ṣe adura fun un, o si gbádùn nibi aisan rẹ, o wa da gẹgẹ bii pe inira kan ko mu u tẹ́lẹ̀, o wa fun un ni asia naa, o pa a láṣẹ pẹlu pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ titi o fi maa sunmọ aaye àábò awọn ọta ti o si maa fi gbigba Isilaamu lọ wọn, ti wọn ba da a lohun; o maa sọ fun wọn nnkan ti o jẹ dandan fun wọn ninu awọn ọran-anyan. Lẹyin naa, Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣàlàyé fun 'Ali nipa ọla ti o n bẹ fun ipepe lọ si oju ọna Ọlọhun ati pe ti ipepe ba jẹ okunfa ìtọ́sọ́nà arakunrin kan ṣoṣo ìyẹn loore fun un ju ki rakunmi pupa jẹ tirẹ lọ, eyi ti o ṣe pe oun ni o níye lórí julọ ninu awọn dukia larubawa, yio ni i tabi ki o fi ta ọrẹ.